Chief Secretary to the Govt


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. No. 293 SATURDAY, SEPTEMBER 22, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Iakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silę.



CHIEF SECRETARY'S OFFICE
2 OCT. 1928


A. Olu'


SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr Earl Sloan
TO STOP
YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

# GBOHUN-GBOHUN.

## OKU DI MEJI OKAN L'OKO.

Jamba ti a gbọ pe awọn ole ti nwọn nja ni oko—oloko ni agbegbe Eko kuro ni jamba yẹpẹrẹ: nilọlọyi ni a sọpe awọn kan ri oku enia kan ti a sọpe o nṣan agbara ẹjẹ ni ilu ti a npe ni Iṣẹri-Oṣin ti ko jina s'Eko ; awọn Ọpa Ọba ti dide si wiwadi ẹniti o ṣe jamba yi, gẹgẹbi a ti gbọ si.

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

### IPADE DẸMỌ.

Awọn ẹgbẹ "Dẹmọ" ṣe ipade Dẹmọ ni ọjọ Satide to kọja ni agogo mẹrin irọlẹ di agogo meje alẹ, ile kun ọna bo, awọn ti o wa nwọn fẹrẹ to ẹgbẹrun mẹrin enia lọkunrin ati lobinrin.

### ALAGA.

Ọgbẹni W. A. Shackleford lo ṣe Alaga ẹgbẹ Dẹmọ ijẹjọ ni ile Afari-ogun dipo Ọlọla Lọya E. Eric O. Moore ti nwọn ti fi sinu iwe ikede ri

### AṢOJU EKO.

Gbogbo awọn ọmọ-ẹgbẹ Dẹmọ fohunṣọkan lori awọn mẹta ti nwọn nfẹ ki o lọ si Igbimo Aṣofin ninu ipade Gbogbo-gbo ti nwọn ṣe ni ọjọ Satide to kọja, ọjọ kẹdogun oṣu yi ni (G.M.H. orukọ awọn mẹta na ni iwọnyi : Ọlọla Lọya Eric O. Moore, Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi Jones ati Councillor Lọya T. Adebayọ Doherty. Ki eku ile gbọ ki o lọ wi fun ti oko c.

### ILU-KỌMITI.

Awọn Ilu-Kọmiti ti ẹgbẹ Dẹmọ yio ṣe ajẹ wọn lọjọ Alamisi ogunjọ oṣu yi (eyi yi ni ọjọ Alamisi ijarun, nibẹ ni nwọn o ti fi awọn enia mẹta na mu ajọ *ibura* ki nwọn to dibo fun wọn ni ọjọ Jimọ ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi ti o ku ọjọ meje si loni.

### IPADE BOMBATA.

Alaga ẹgbẹ Dẹmọ ti ọjọ Satide to kọja (Ọgbẹni Shackleford) fi ipinu si wipe Ipade Ẹgbẹ Dẹmọ miran tun mbẹ loni fun ẹgbẹ papa fun awọn ẹniti yio le dibo—Ọlọla Lọya Moore ni yio ṣe alaga.

### EJI NLA.

Kini aseko pipe awọn ọmọ ẹgbẹ to fun ni ojo kan ni on bẹrẹ, ki a ma dena penu ojo na rọ titi kọja agbarọ alẹ ki ọ to da. Gẹgẹbi o ti jẹ wipe awọn ọmọ-ẹgbẹ yi ni itara si ipade wọn, nwọn ko tilẹ mọ wipe ojo kan nrọ nibikan, bẹni nwọn t' ori bọ wa ni iyẹn, gasa ! oṣumare jare ojo.

### ỌJỌ RE 'BI ANA.

Ni ọjọ Alamisi ijẹrin ti nṣe ogunjọ oṣu yi ni o di o didi ọdun marun gbako ti awọn ilu papa ẹgbẹ Dẹmọ yan Ọlọla Lọya (*Ologbe*) J. Egerton Shyngle, Ọlọla Lọya Eric O. Moore ati Ọlọla Dokita C. C. Adeniji-Jones si Igbimọ Aṣoju ilẹ yi, fun aṣoju wọn.

### IWE ILERI.

Ọlọla Eric O. Moore ka iwe-ileri tirẹ si eti igbọ gbogbo awọn ọmọ-ẹgbẹ ni ipade tokọja, iwe eyiti nwọn sọ ohun ti nwọn yio le ṣe ni Kansulu,

Bẹni Lọya T. Adebayo Doherty papa ka tirẹ, gẹgẹ bi Ọgbẹni Shackleford, Alaga ti palaṣẹ fun wọn ; Ọlọla Dokita Adeniyi-Jones ko si ni ile ẹniti ẹgbẹ Dẹmọ tun mu ṣi kẹta awọn ti nwọn yio dibo fun.

### ẸGBẸ DẸMỌ.

Gbogbo ẹgbẹ Dẹmo gba awọn mẹtẹta ti nwọn tun nfẹ ṣẹṣẹ yan lo si Igbimọ na l' ọjọ Satide ti nwọn pe, gẹgẹ bi ṣawura ti awọn Ilu Kọmiti wọn ṣe lọjọ Alaruba ojo kejila oṣu yi ni Ẹhingbẹti.

### "TOWN COUNCIL"

Awọn onilu nṣe oju agbara a dara dara si Tokunboh Street nisisiyi, bi nwọn ba yẹri ti ibẹ, ki nwọn jọwọ rant awọn adugbo wọnyi :

1. Macaulay Street,
2. Carrena ,,
3. Oluwọle ,,
4. Inabere ,,
5. Branco ,,
6. Adu ,,

ati awọn adugbo miran gbogbo ti awọn "Town Coucil" papa ri wipe o dara lati ni oju agbara fun anfani lati ma lo omi d po, omi ti awọn ara adugbo miran nda si gbangba ode, ti o si nda rẹgun ti ki isi fun enia ni irọrun tobẹ lati ma rin gere kọja—Ẹ ku iṣẹ o, a si fi eyi so Lọya Doherty lọwọ.

ỌLỌLA WILSON, K.C.B.,

A gbọ wipe oyinbo Ọlọla Samuel H. Wilson, K.C.B., G.C.M.G., ati Iyawo rẹ ti ba ọkọ "Egori" lọ si ilu Aganyin, Accra ni ọjọ Satide to kọja.

BUXTON MACAULAY.

Anu ṣe ni lati gbọ ti iku Ọgbẹni Thomas Fowell Buxton Macaulay—ẹgbọn Ọgbẹni wa Herbert Macaulay, ni ọjọ Satide to kọja.

A ki gbogbo awọn ẹbi, aya patapata pe nwọn ku ọfọ na—Ki Ọlọrun sun ọjọ si waju o.

J. BAGAN BENJAMIN, C.E.,

A gbọ wipe awọn Ilu.Komiti ṣe ariyanjiyan lori mimu Ọgbẹni Benjamin ati Lọya Doherty lati lo si Kansulu, ni ajọ ti nwọn ṣe larin ọsẹ to kọja, ṣugbọn gẹgẹ bi a ti gbọ wipe awọn ẹniti o mu Lọya Doherty lo po ju ti Ọgbẹni Benjamin lọ, nipa eyi nwọn fi ipinnu le lori pe awọn mu Lọya Doherty, lẹhin eyi a tun wa gbọ wipe Ọgbẹni J. Bagan Benjamin lọ da imura mu fun ararẹ lati lo si Kansulu na. Taruku-taruku tata! taruku-taruku !! ode ọyọ.

---

SHAGAMU AND ITS NEEDS.

By J. A. O. Shomade native of Ipẹru, Ijẹbu Rẹmọ.

---

To the Editor of *Eko-Akete.*

Sir,

During the reign of Her late Majesty Queen Victoria Shagamu was an important district in what was then known as the Colony of Lagos, and not only that a European political officer was placed there together with police and Printing Department but also an hospital and dispensary with a resident Doctor for the benefit of the thirteen towns comprising Ijẹbu Remo Province. Why these were removed I do not know. Now the people are more civilized than then and the population is increasing very rapidly and trade is increasing and many people are doing business direct with England and this is causing great hardship we therefore implore the Government to again encourage the forward movement by placing a well equipped Post Office prison Department Hospital and Telegraph at Shagamu and branches should be opened at Ipẹru also.

We have heard sometime ago that the Railway authorities are contemplating to extend a branch line to Ijẹbu-Ode and Shagamu and we believe this is the time for it there should be no delay there is sufficient produce to make it pay. I hope this my humble petition will reach the ears of the Government and something done for Shagamu and districts.

Yours faithfully,
J. A. O. SHOMADE.

---

ORI IV.

IṢẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KẸDOGUN.

---

Sibẹsibẹ gbogbo awọn ti a daruko wọnyi, awọn iku iṣẹ, wa ninu awọn ẹniti a ka mọ awọn Ọkọwe pataki ni aiye; igba aiye Elizabeth ati ti James I si jẹ asiko ti iṣẹ iwe kikọ gbilẹ ju, ti o si ni arinrin ju ninu itan ilu *England.*

Ni aiye Charles I. Cowley ṣe onirun iṣẹ pataki ati iṣẹ ẹlẹge fun ijọba. O ṣiṣẹ akọwe (*Private Secretary*), fun awọn ti o nṣe ti Ọba, lẹhina ni awọn wa fi ṣe akọwe (*Private Secretary*) Aya-ọba lati ma ka ati lati ma kọ adutu iwe ti o nlọ larin Charles I, ati Aya-'ba rẹ; fun ọdun pupọ tọsan-toru ni o fi nṣe iṣẹ yi.

Bi Cowley ti nṣe ti Ọba bẹni Milton nṣe Akọwe ni ede *Latin* (*Latin Secretary*) fun Ilu (Commonwealth), lẹhin na ni o waṣe akọwe fun Olu tu-Ilu (Lord Protector) Bẹni iṣẹ ti Milton kọ ṣe laro ko ju ti Oluko ni ile iwe lọ. Dr. Johnson sọ pe "Ko si tabita ... pe tokan-tokan ati tara-tara ni o fi ṣiṣẹ oluko bakana bi ti gbogbo awọn iṣẹ ... ti o ṣe" Lẹhin ti ilu roju, ti nwọn fi jẹ Ọba, ti iṣẹ Milton duro, ni o sẹṣẹ wa ... eyi ti o jẹ pataki ninu iṣẹ iwe ti o kọ; Ṣugbọn ki o to bẹrẹ si kọ eyiti o jẹ pataki iwe rofọ itan ... orin (Epie) ti o ṣe, o ri ... pe lẹhin "... iwe atata ti on ti kọ," o t... ki on tun ... balẹ ki on kọ ... gbọn lọna gbogbo miran.

Ki işe laiye Ọba kan mọ ni Locke şişẹ Ọba; O kọkọ şişẹ akọwe Board of Trade ni aiye Charles II, lẹhin eyi o şişẹ Commissioner of Appeals ati ti Trade & Plantations ni aiye William III. Ọpọlọpọ ni awọn Okọwe pataki ti a mọ ti o şişẹ Ọba ni aiye Ọba Obirin Anne. Addision şe Secretary of State; Steele şe Commissioner of Stamps; Prior şe Under-Secretary of State, lẹhin na ni o wa şe Ambassador ni France; Tickell şe Under Sectrary of State ati Secretary to the Lords Justices of Ireland; Congreve şe Secretary of Jamaica; Gay si şe Secretary of Legation ni Hanovex ni gasikia, bi o kanran ki işẹ-şişe mu ọlọgbọn tabi Oloye enia ma le şe işẹ Ọgbọn ori tabi işẹ iwe kikọ, a ni le şe işẹ wọnyi daradara ni. Voltaire tẹnu mọ, otitọ si ni o sọ, pe, Ọna işẹ gbogbo ati ti işẹ iwe Ọkana ni; ki a şe ọna mejeji yọri nfẹ ãyan on ero, ẹkọ on Ọgbọn ati ero on isẹ—, apapo eyiti Lord Bacon pe ni ohun ti o dara ju ninu ẹda enia.

A tilẹ sọ pe Ọlọgbọn abami enia papa kole şe iwe kan ti o damọnran nipa işe ẹda enia ayaşebi o ba ti lo mọ enia ti o si mọ aiye tẹlẹ.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## ỌLỌLA DOKITA JONES ATI "THE NIGERIAN NATIONAL DEMOCRATIC PARTY"

Ninu ipade ti ẹgbẹ Dẹmọ şe ni ọjọ kẹdogun oşu yi ni Ile Afari ogun, ọgbẹni Shackleford ti o jẹ Alakoso ipade na sọ wipe gẹgẹbi o ti jẹ wipe Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi-Jones M.B., CH.B., gbọlọfẹ lọ si ilu oyinbo nisisiyi awọn Kọmiti fi ipinnu si ninu ipade wọn pe awọn tun mu pẹlu lọtẹ yi lati lọ si Kansulu awọn si fẹ mọ bi o tẹ ọmọ-ẹgbẹ lọrun gbogbo wọn sọ wipe o tẹ awọn lọrun.

Lẹhinna ninu ọro Oloye Tijani Oluwa o tun fi ẹnu kan ọran Dokita Jones wipe kosi ni ile şugbọn o mbẹ ni itosi wọn, awọn si nwo bi awọn ti duro yi, nitorina awọn tun mu pẹlu lọtẹ yi, lẹhin eyi li o wa rohin işẹ ribiribi ti olukuluku wọn tişe fun awọn ni Igbimọ na.

## MOORE, JONES ATI DOHERTY.

Ni eyiti gbogbo wa mọ awọn mẹta ti ẹgbẹ "Dẹmọ" yio ran lọ si Igbimọ Aşofin (Legislative Council) ninu eşu yi (Moore, Jones ati Doherty) ti gbogbo ẹgbẹ yi si fi ipinnu si ori awọn ẹni mẹtẹta na, a rọ wipe, ki yio si ẹniti yio gba ẹhin ba ẹbọ jẹ ninu gbogbo ọmọ ẹgbẹ na lati oke de ilẹ.

KEKERE AWO.

---

## IROHIN IKU MR. DANIEL ADEKỌYA.

Anu şe mi lati sọ nipa iku Mr. D. Adekọya ọmọ Ọbadina Inakoju Gadanji ti Itantẹbọ Street Ijẹbu Ode ti o ku ni magodo, oko Işẹri. Adupẹ pe Iya rẹ ku ni ọjọ 18/8/27. Mr. Adekọya ọmọ rẹ si ku ni ọjọ 5/9/28, ni agogo mẹjọ alẹ kọja işẹju marun. Mr. D. Adekọya o jẹ aburo Ọlọla James Sholu ikan ni ninu awọn ti o ba Ọlọrun rin ni o. Ki Olodumare jọwọ ba wa şe itọju awọn ọmọ rẹ. Amin.

Ọpẹlọpẹ Mr. Oyekan ikan ninu ọmọ ọgbẹni Oyegunşẹn Ọlọla Ipẹru lo şe ajo oku Mr. D. Adekọya ọmọ Mr. Ọbadina Inakoju Gadanji. Ki Ọlọrun jọwọ ba Mr. Oyekan tọju ile ati gbogbo ini rẹ, ati gbogbo awọn ti o şe ajo ni ibi oku na, Amin.

O ya mi li ẹnu pupọ wipe ọmọ jaguda wole lọ gbe pọtimọnto. Rev J O. Shopẹkan ati aşọ oye rẹ ati awọn iwe rẹ gbogbo.

Ẹ jọwọ ẹnyin Ijọ Enia Ọlọrun mimọ, ẹ ba wa gba adura fun oluwarẹ ki Ọlọrun ọwọ ba wa tu aşiri oluwarẹ, aşiri ẹni ti o gbe Pọjtimọnto lọ lai pẹ yi.

J. A. O. SHOMADE.

---

## A ŞE NI LODE KO TO TILE, ILE N'IKU WA O.

O jẹ ohun ẹdun wa lọpọlọpọ nigbakugba ti a ba nranti pe Ọgbẹni Herbert Macaulay ko si ni arin wa loni, ati pẹlu pe, bi a ti nwi lowọ yi alayọ nyọ bẹni lotọ ni eyini, nitoripe Bibeli ti sọ pe ẹniti nyọ ẹ ma ba wọn yọ, ẹniti nsọkun ẹma ba wọn sọkun pẹlu, ẹ ma fi alafia ba gbogbo enia gbe ẹ ta kete si ohun ti şe buburu ki ẹsi fi ara nyin si ohun ti şe rere, njẹ bi a ti wi yi ọpọlọpọ ninu wa ko ha nwa işubu ọmọlakeji rẹ bi? Ko nwa ki ọmọlakeji on ku tabi ko kuro ni ilu fun on kini yẹn ha da, ti a ba tilẹ wipe o kuro nilu fun ọ, ha wa, ẹ rọra ẹdi ki a ba yin sa. Ojojumọ ọte, şişata gigan, tabi ki a ma tuna aşiri ọmọlakeji wa, ẹgbọ na ibo tilẹ ni iyẹn lọ to bọ irọ patapata gba ni ko lede ẹhingbẹti, awa ara wa la tun şe ara wa, iba ma şe bẹ ni, oni iwe irohin ti nwọn npe ni Lagos Daily

Times, enia dudu kanna ni gbogbo wa nṣe lati Awusa Jẹkiri, ni papa gbogbo Africa.

A tilẹ fẹ bere kini kan lọwọ Daily Times ni pataki niti gasikia ni ede awọn Awusa, kini ẹṣẹ ti Ọgbẹni Herbert Macauley ṣẹ yin o? Ẹ wi ka gbọ, tabi Eṣugbayi Eleko lo ṣẹ Daily Times ni ki o to le tobẹ, o di yin lọwọ lẹnu iṣẹ yin ni bi? Boya o le jẹ pe ẹ ṣẹṣẹ gba Akawe titun kan eyi to jẹ pe ko mọ ohun ti on kọ, ala katakoto wo ni yẹn o, kayi rẹ, akọwe agbegi dẹnu, to ṣẹṣẹ wọ ilu wa, mo gbọ pe a nkọ we, mo la ra A. B. D, bi iwọ ba ronu tirẹ wo daradara ti o si ni ero to pe, iru Ọgbẹni Herbert Macauley ni ẹniti o iyẹ ti iwọ le ma sọrọ odi bẹ yẹn si, iba sin bo ba jẹ pe ori ẹbi kan, ni apa ọdọ rẹ ni, Ọgbẹni yi ko mọ ṣẹ o ṣugbọn a ko le ba ọbọ tirẹ jawura, bo ti wu ko le wẹ to, o le funfun ko da bi oyinbo enia dudu kanna ni a ma pe o, ko dẹ le wa di igbana ka wipe iwo ni oye Eleko tọ si, ka ma ri agbẹdọ. Esuru tirẹ ko ya ni yan Ila ga fun ẹkọ, bi bẹ si kọ, jade lọla ko du oye Eleko, pe o fẹ jẹ oye ka wa wo, ha! ha!! ha!!! iru akọwe wo ni yẹn o, iwọ fẹ wipe iṣẹ ti Ọgbẹni Macaulay nṣe ko kan ọ kọ na? Ko buru o fẹrẹ kan ọ na, dẹju ko ri mu o akowe, ta ni tilẹ le wẹ ko yan kaurinkan ninu yin, tabi tani aba ṣi abiya rẹ wo kẹ ti gbogbo rẹ ko ni dọṣẹ.

Iba jẹ pe ẹnyin nifẹ ilu yin lọkan ẹnyin jẹ tẹ iru iwe bẹ sode fun gbogbo awọn enia ati fun awọn alabo wa, pe Herbert Macaulay must be gagged, lotọ laipẹ ọrọ rẹ na si jẹ bẹ, njẹ iwọ ṣe rere niyẹn bi? Ẹda to wu to nlulu ibajẹ Ọlorun Olodumare ko ni jẹ ko dun, kini Baba enikan ṣe ti Baba ẹnikan ko ṣe. O ṣe, bi akọni ba ku a fida la ilẹ, bi a ba nka nisisiyi, a o ri ọpọlọpọ awọn akọni eyi to jẹ pe igbi aiye yi lu ti kole gbe ori titi fi di oni yi, ṣugbọn mo fẹ ki ẹ ranti pe iwe mimọ sọ bayi pe Olododo yio ma wa ni iranti titi aiye ko si bo ti wun ko ri ti awọn ilu lejfi Herbert Macaulay silẹ lai ranti ki nwọn wa wipe tirẹ a la kọ loju ni wọn ma wa tẹle, nitori pe alai ko lojuti akọwe Daily Times, Herbert Macaulay May God the Fathe A l m i g h t y grant you long life and prosperity, that you may be leading us more, Work on, brave heart, your help is needed, lai ko fa gun lọ titi, ọdun mẹfa yio ma ku ola o, ranti pe oju oro ni leke omi, oṣibata ni leke odo, ni agbara Edumare iwọ yio leke, rikiṣi ko logun Edumare lo ntun mọ rikiṣi a mi nu ẹnu awọn ọlọtẹ nwọn ko ni ri yin gbeṣe a kodi ki pa ifa, Iba mi aṣẹ iba, Agbe nalẹ ki pa ọpẹlẹ, agbe ṣire ki pa Oge, Babalawo ki npe ri rẹ nibi, tabi oni ṣegun ni npe ri rẹ nibi, eke tabi ẹdalẹ ni npe ri rẹ nibi, Igbe ni Ara ba wọlẹ igbe bẹ re ma ri, Ọgbọ ti gba eyiti mo wi yi igba ti gba ọrọ ti Okete ba sọ ji ilẹ gba bi ọmọde ba kegbe ninu igbo gbohungbohun a gba sa fi awọn ọlọtẹ silẹ, dakun maja fi ọwọ lẹran, ẹnikan ko mọ ohun ti Ọlorun yio ṣe, ṣugbọn daju-daju Olodumare ki ṣe ibi, Ọba Adakẹ dajọ Ọba awọn Ọba, Oluwa awọn Oluwa, on nikanṣoṣo ti ole ṣe ohun iyanu nlala yio gbe yin leke abinu ẹni. Kini Macaulay ṣe alai ni ero to jinlẹ to lori, o sa ni ohun ti Ọpọn ṣe ti wọn fi kan ni ran, adiẹ kọwe oyinbo mọ ti, ẹma binu Ori fi fila dedi o, ẹniti ko iti ku ko mai ti gbọn iku lọ, Itadogun ku si dẹdẹ ọjọ ẹlẹsin kọla ni ẹnyin ọlọtẹ nba kiri, ko ma si orukọ rere ninu arijẹ ninu idaru o, nitori ọjọkanjọkan nbọ ti idaru yio ko ẹhin, iwọ ti o ti njẹ ninu idaru ṣọ jẹ o.

TẸNI-MA-SUNWỌN.

## Olusakin's Column.

### BIRTH.

News reached us from London that on Tuesday, the 28th August, 1928, at 27, Welbeck Street, London, a son was born to Lady Baddeley, wife of Sir F. M. Baddeley, K.C.M.G., Barrister-at-Law, Chief Secretary to the Government, Nigeria. Congratulation.

### WELCOME.

We welcome Captain J. G. Byrnell, Head Printer of the C.M.S. Press, who has been touring Ibadan, Oshogbo, Ilesha and Ile Ifẹ that ancient Yoruba Town with his wife, and has seen the ancient relics of that town through the courtesy of Alaiyeluwa the Ọni of Ifẹ, arrived Lagos on Monday the 17th instant.

### CANDIDATURE MANIFESTO.

We are publishing to-day the first instalments of the texts of manifestos of the candidates who are offering themselves at the forth coming general elections.

At present, we hear of only five candidates viz:—Mr. Eric. O. Moore, B.L., Dr. C. C. Adeniyi-Jones and Mr. T. Adebayo Doherty, B.L., who are standing as Democratic Nominees.

Then, Mr. J. Bagan Benjamin, C.E., who styles himself as an "Independent Democrat" and Mr. E. M. E. Agbebi, B.L., who is standing as an Independent Candidate.

We have only got the copies of only two of these candidates manifestos as are being published elsewhere. As Dr. C. C. Adeniyi-Jones is now away on holidays in Europe, we have not got his manifesto

As at present, we are offering no comments upon any of these candidates as the circumstances which surround each and every one of them is not hidden from the electorate of Lagos.

There was a division in the Demoncratic Party camp, when the Committee were making their selections; although the majority carried in favour of Mr. T. A. Doherty, B.L., Mr. J. Bagan Benjamin, C.E., refused to fall in with the majority and that is why he now stands as an "Independent Democrat."

However, we expect every member of the Nigerian National Democratic Parŋy to stand firm by the side of the Party's nominees and also to stand firm where conscience is concerned for the "Democrats" and we can only say stand unmovable for the "Democrats" and form your judgment.

"Trust in God and do the right."

*The Lagos Daily News* 18/9/28.

---

THE RETIREMENT OF MR. F. O. WILLITS, ASSISTANT SUPERINTENDENT OF THE LINE (TRAFFIC).

There was a Social Gathering at the Traffic Training School, Ebute Metta, on Saturday, the 15th September, 1928, at 5 p.m., when the African Staff of the Superintendent of the Line's Office, Transportation Department of the Nigerian Railway made a presentation to Mr. F. O. Willits on the occasion of his retirement after 18 years' meritorious, length and faithful service.

The gathering included some senior European and African members of the Nigerian Railway.

Mr. J. D. Akinhanmi, Chief Clerk of the Department spoke many complimentary things about Mr. Willits' career since he has joined the service in a language befitting his ripe knowledge and intelligence.

The address was duly read by the Secretary Mr. E. A. Sule and presented to Mr. Willits. Several speeches were made by D. H. Elias, Esq., M.C., the Superintendent of the Line and Mr. H. King Paul, after which Mr. Willits replied in a most suitable manner. Light refreshments were subsequently served.

The second part of the Programme cannot be maintained owing to the inclemency of weather, when it was adjourned to Tuesday the 18th instant, at the Railway African Staff Tennis Grounds, Ondo Street, West, Ebute Metta at 5 p.m., when matches were played between Messrs. A. I. Shaşeyi and C. T. Oshinaike for 2 *versus* E. A. Oni and E. A. Tytler for 6.

And Messrs. S. A. Coker and E. A. Shiwoku for 2, *versus* J. A. Ajala and J. B. Shusi for 6. *Referees* Messrs. E. O. King and S. A. Adu.

Conspicuous among those present were:—J. W. Fenwick and Mrs. Fenwick, H. A. Freeland Esq., S. W. Shinn, Esq., F. W. Doggett Esq., G. Alderson, Esq., C. Mitten, Esq., J. T. Nelson Cole, Esq., B.L., Dr. K. Faderin, M.B., CHB., P. J. C. Thomas, Esq., J. A. Odufunade, Esq., E. C. Nelson Scott, Esq., H. S. A. Thomas, Esq., A. J. Marinho, Esq., Jnr. N. F. Williams, Esq., M. O. Ebinisi, Esq., I. F. Maye, Esq., and Mrs. Maye, A. O. Beckley, Esq., B. O. Taylor, Esq., D. A. Bright, Esq., Simeon Olulode, Esq., E. A. O. Bright, Esq., J. A. Tylter, Esq., E. A. Johnson, Esq., S. O. Ajayi, Esq., Mrs. Georgiana Bailey, H. King Paul, Esq., C. D. Richards, Esq., Ọlamide Ajayi, Esp., D. Olubi, Esq., S. A. C. Sholu, Esq., Bisruyu Laguda, Esq., E. A. Bukọ, Esq., E. I. A. Joseph, Esq., N. A. Young, Esq. Ajayi Ọbanikoro, Esq., J. A. Ashcroft and host of others.

We congratulate Mr. and Mrs. Willits and wish them long life of usefulness to enjoy the deserved and well merited pension.

We extend our congratulations to the Secretary and Committee Members for the brilliant "Send off".

---

RUMOUR OF IMPENDING CHANGES IN THE ANGLICAN DIOCESE OF LAGOS, REPRODUCED FROM THE LATEST ISSUE OF THE "AFRICAN WORLD."

"I understand that on his return from the present furlough the Right Revd. Bishop F. W. Melville Jones, Bishop of Lagos, will retire. The veteran Bishop Oluwole will also retire and it is said that the Archdeacon of Lagos, Venerable T. A. J. Ogunbiyi will ask for retirement. No Assistant Bishop will then be resident in Lagos, but at Abeokuta and at Ondo. To fill the vacancies the name of the Revd. M. S. Cole, now Vicar of Christ Church, Lagos, is mentioned and for the latter place the Revd. S. C. Phillips, now Superintendent of the district.

The name of the Right Revd. Bishop A. W. Smith now Assistant Bishop in the North is mentioned in connection with the Bishopric of the Diocese when it becomes vacant."

---

OBITUARY.

It is with deepest regret we chronicle the death of Mr. Asani Ọkunrinjẹjẹ which sad event took place at his residence 14, Olo... Street, Lagos on Monday night the 17th September, 1928

Mr. Ọkunrinjẹjẹ was a kind hearted man polite, and popular, he was a Staunch Committee mem-

ber of the "Nigerian National Democratic Party" and also a member of the Asaru Din Society in which Mr. Abibu Oki Balogun is President.

Mr. Ọkunrinjẹjẹ was a good friend to those who came in contact with him. A good adviser in time of trouble to his family and to all those who were used to him.

To his wives, children, Madam Layide Taiwo, Madam Ayi Ọkunrinjẹje, Mr. Nutalabi Lawani, and to the bereaved families, our heartfelt sympathy. Surely Mr. Ọkunrinjẹjẹ was a father in "Mohammedan Israel".

May he rest in peace.

OLUṢAKIN.

---

# EKO AKETE

EKO, SATURDAY, SEPTEMBER 22, 1928.

## NIGBATI ỌSAN NṢE, KI L'ORU NWO?

Lati igbati ipalẹmọ yiyan enia mẹta si Ajọ Igbimọ Aṣofin *Nigeria* ti gbojikan lẹnu ọjọ tabi ọsẹ diẹ sẹhin vi; ninu ipalẹmọ ti Ẹgbẹ Dẹmọ mu ni imu totọ; lati igbana ni awọn Iwe-Irohin bi meji tabi mẹta ni igboro ilẹ yi ti bẹrẹ si ṣata awọn pataki pataki Ẹgbẹ na papa Ọgbẹni Herbert Macaulay ẹniti o jẹ baba Ẹgbẹ na nipa dida silẹ:

A ṣebi ilu Eko yi ni awọn Alayọnusọ yi ti wa nigbati a fi ori Ẹgbẹ Dẹmọ sọlẹ, talo mu awọn "Lapanpa" wọnyi lọwọ dani pe ki nwọn maṣe da Ẹgbẹ ti wọn silẹ; orişirişi Ẹgbẹ kọ ni awọn kan ti da silẹ ni ọpọlọpọ ọdun sẹhin abọ gbogbo awọn Ẹgbẹ na da loni? A le sọ pe nitoripe gbogbo ilu nwọtọ Ọgbẹni Herbert Macaulay lẹhin fun iṣẹ ribiribi ti on ṣe fun rere ilu loju mejeji, ni eyi si di iyọrọ ti o mbo awọn Ẹlẹrẹkẹ ebu wọnyin lati ori d'ẹsẹ, a ṣebi asiko ni yi fun awọn Ẹgbẹ ti nwọn npe ara wọn ni Ẹgbẹ-Ilu lati ṣe gudugudu meje fun yiyan Enia mẹta sinu Ijọ Igbimọ Aṣofin, ti nwọn ba to lẹnu rẹ; ni ọdun karun tokoja a mọ bi Ẹgbẹ kan ti o fẹ ba Ẹgbẹ Dẹmọ t'ori gba'ri, ti sare asa f'oju gun 'gi nipa yiyan awọn Ẹni mẹta ṣiwaju ti nwọn si bo 'lẹ; o ha dara pe nitori ẹ ko le ri ibi duro si ni ibiti Ẹgbẹ Dẹmọ ba wa nitorina ki ẹ ma rọjo ebu si ẹniti o da Ẹgbẹ silẹ: Iọju wa, iwa ojo (*Cowardice*) to ju eyilọ kosi ṣugbọn ẹgan ko ni ki oyin ma dun, kaka ki awọn enia wọnyi dakẹ nigbati nwọn mọ pe nwọn ko to ila de, nṣe ni nwọn joye aritẹnimọwi, afi apadi janran bo tirẹ mọlẹ. Nisisiyi ti a ti mọ iye awọn enia ti yio lọ si Ajọ Igbimọ Aṣofin ti a nwi yi o yẹ ki gbogbo ilu parapọ lati lọwọ ninu iṣẹ yi; ọjọ didibo nku fẹfẹ, kosi ju ọsẹ to mbọ lọ, ọjọ kejidilọgbọn oṣu yi.

O yẹ ki gbogbo awọn ti nwọn to dibo ti nwọn si ti fi orukọ silẹ lẹdun ni mura giri lati tete de Ile-Idibo lọjọ na ati lati dibo fun awọn Ọgbẹni ti ọkan wọn ba daniyan fun. Lasan ni awọn ti nwọn nsọrọ odi si M a c a u l a y nṣe nwọn mọ dajudaju pe lati igbati a ti bi ọmọ ẹṣin lo ti ju ọmọ agutan lọ iwa abinuku ti awọn Iwe-Irohin meji mẹta yi nhu si awọn Olotu Ẹgbẹ Dẹmọ ko ṣẹ lori irira ti nwọn ni si lilọ siwaju Ẹgbẹ na, irufẹ awọn Iwe-Irohin wọnyi ni nwọn nda aba kaba fun Ijọba ti nwọn si nṣi nwọn lọna li ẹkọkan, bi a ba wadi gbogbo rikiṣi yi, a o ri pe Enia Dudu ni a o ba nidi rẹ, bẹ Dẹmọ ko sọpe ki onitirẹ ki o maṣe; bi awọn enia wọnyi ripe ẹnu wọn ko to 'lẹ de ipo pe ki ilu le fi ma tẹle wọn, nwọn a sọ ẹjọ di ẹjọ oloko ẹṣin, nipa yiyọ ṣuti si awọn Ijimi ijimi ninu Ẹgbẹ na, oni kọ bẹni ki ṣe ana ti awọn enia wọnyi ti nfi ibajẹ ṣe ayọ nipa bibu ẹniti kotọ wọn ti oniyẹn ki pẹkẹ lu gbogbo ebu ti nwọn mbu on wọnyi, ṣugbọn ti o jẹpe sibẹsibẹ awọn ara'bi wọnyi ko dẹhin lẹhin rẹ b'a je ni b'a o ba ni, iwọn la bani ṣọta mọ.

A dupẹ lọpọlọpọ pe gbogbo iyọṣuti si wọnyi ko di Ẹgbẹ Dẹmọ lọwọ bẹ si ni ko tu wọn ni irun imu lati ma ba iṣẹ wọn lọ ki awọn Buni buni wọnyi tẹpa mọ iṣẹ ebu wọn lojojumọ tabi lọsọsẹ, ṣugbọn ọkan ni:—

Ara Alanpọ̀ lopọ si
T' Elepo diẹ ! ! !

## IPADE DẸMỌ.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Awọn ẹgbẹ "Democratic Party" ṣe ipade Gbogbo-gbo ni ọjọ Satide ọjọ kẹdogun oṣu yi, ni Ile Afari-cgun (*Glover Memorial Hall*) labẹ Alakoso Ọgbẹni W. A. Shackleford ati awọn Ojoye Onifila-funfun Oloye Eletu Odibo, Tijani Oluwa, Oloye Olumẹgbọn, Oloye Ọlọtọ, Abagbọn Ashọgbọn ati Saka Oshodi pẹlu awọn isangbe ti a ri loke bi awọn Ọlọla Lọya Eric. O. Moore (Alaga), Ọgbẹni Thomas, H. Jackson (Akọwe ẹgbẹ), Lọya T. A. Doherty, Daddy Thompson, Ọgbẹni L. A. Cardoso, Ọgbẹni Omvery John, Ọgbẹni Baptist, Ọgbẹni Scott, Ọgbẹni Martins, Lọya Latunde Johnson, Alaji Abudu Salami Davies, Brimah Igbo, Lemọmu Amọdẹ, Lemọmu Alfayat, Lemọmu Lawani Aguda, Alufa Bello Arọwasi, awọn Lemọmu m i r a n pẹlu awọn isọri-isọri nla-nla ti a ko le ma daruko.

Ajọ bẹrẹ ni agogo marun kọja iṣẹju mẹdọgbọn.

Alaga Ọlọla Moore sọ wipe awọn nreti Akọwe ẹgbẹ (Jackson) ni ko jẹki ẹgbẹ ti bẹrẹ ọrọ, ko pẹ lẹhin eyi ni Ọgbẹni Alẹṣinlọyẹ Willimas pẹlu Ọgbẹni Jackson de.

Alaga Moore dide lori aga, Ọgbẹni Shackleford joko si ipo alaga o si ṣi ẹgbẹ.

ỌGBẸNI SHACKLEFORD :—A ṣe ipade Kọmiti nihin larin ọsẹ yi, a si fi ipinnu le e wipe, awa mu Moore, Jones ati Doherty lati ran lọ si Igbimọ-Aṣofin ninu oṣu yi, a si ri wipe eyiti awọn ṣe na o dun mọ nyin ninu, ẹ si lowọ si i pẹlu.

Ẹniti o ba ni ọrọ lati sọ ki o jade ki maṣe ni ikunsinu fun ẹnikẹni pe nwọn ko jẹki on sọrọ ninu awọn mẹtẹta ti awọn mu ni, ẹniti o ba ri wipe gbogbo wọn, awọn meji tabi ẹnikan ninu wọn ni on ko fẹ ki oluwarẹ jade ki o sọ, lẹhinna awọn si nfẹ bi awọn mẹta na (Moore Jones, ati Doherty) ti awa mu na ba tẹ nyin lọrun.

Gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ si sọ wipe awọn fẹ gba nwọn, o tẹ awọn lọrun.

ỌGBẸNI JACKSON :—Mo gba gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ ni imoran pe ki a gba awọn mẹtẹta ti awọn ilu-Kọmiti mu.

Ọgbẹni Thompson, Alaji Davies ati gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ si sọ wipe awọn mẹtẹta tẹ awọn lọrun.

JARIỌGBE ONIWAKA :—A gbọ ohun ti ẹ wi, awọn mẹta ti ẹgbẹ mu ni awọn na fẹ, ṣugbọn ohun ti o ku ni wipe Ọgbẹni Makọli ti awọn nfẹ ki iṣe wipe awọn ngba kini kan lọwọ rẹ, on kọ ni gbogbo awọn bimọ fun, o ngba ara awọn ta fun ọpọlọpọ nkan, bi ohun kan ba delẹ ti awọn ba lọ ba a loru dudu lẹsẹ kanna lo ma dide, lo ma sọ fun awọn wipe ki awọn lọ joko, on yio ri awọn Oyinbo fun awọn, ẹ maṣe jẹki awọn ranti ore ti Makọli nṣe fun wa, ẹ maṣe jẹki o di igba na tan, ki awọn maṣ tun ri oju nyin nilẹ mọ o, ọrọ ti awa obinrin ko ju bẹ lọ.

ỌGBẸNI SHACKLEFORD :—Emi nko jẹki awọn awọn Lọya Moore ati Lọya Doherty awọn ẹniti o fẹ lọ si Igbimọ jade ki nwọn sọ ti ẹnu wọn, bi nwọn tile ṣe fun ilu nigbati ilu ba gbe ẹru wọn ka wọn lori.

ỌLỌLA MOORE :—Mo ki gbogbo ẹgbẹ patapata, ọrọ mi oni yi ṣoki ni nitori ẹniti o ba fẹ ṣe nkan ki ileri tobẹ: mo tun nfẹ lọ si Kansulu lọtẹ yi, ko su mi arara, ni oni yi lo di ọdun karun, ti mo ti ke ba awọn ilu p'a alaru ni, mi ki nwọn di ẹru wọn ru mi, mo ti mbẹ ninu Igbimọ ri fun ọdun mẹfa, ẹ si tun di ẹru ilu ru mi, mo ti sa gbogbo agbara mi ni gbogbo igba ti mo wa mbẹ.

Mo si tun nfẹ lọ lọtẹ yi, mo ke si nyin pe ki ẹ ran mi lọ lati tun mi ba iṣẹ ilu na nişo, nitoripe ko su mi arara mo lẹ ṣe gudugudu meje ti ọdẹ nṣe fun ibo ti mo tun nfẹ ki ẹ di fun mi lati tun ma lọ ṣe iṣe nyin, gẹgẹbi ẹ ti sọ wipe mo tun tẹ nyin lọrun lati tun lọ.

Awọn ohun ti o mbẹ ni aniyan mi lati tun mura si gidigidi ni :—(1) nipa ọran ẹkọ iwe awọn ọmọ wa, gẹgẹbi o ti jẹ wipe ẹkọ ni pataki fun awọn ọmọ wa, ki nwọn fi le ma ri iṣẹ ṣe daradara, ọpọlọpọ awọn ọmọ wa lo di ọmọ ipata, omiran ẹwẹ nrin gbanraye kiri lai ri iṣẹ ṣe, ti a ba njagun nipa ẹkọ wọn yio jẹ ohun irọrun fun wọn, o ṣe tan Oyinbo ti awọn Ijọba fi ṣe Alabojuto ẹkọ nisisiyi je Oyinbo pataki, awọn Ijọba ko fẹ ki awọn ọmọ wa ni ẹkọ tobẹ mọ bi ti lailai, ẹniti o ba si ma ṣe Olukọ awọn ọmọ ile-ẹkọ nisisiyi Ijọba yio kọ ni ẹkọ daradara, ki o to le ṣe Olukọ, iṣẹ pataki ni mo fẹ ṣe si idi yi ti mba le de ibẹ.

(2) Nipa awọn ọmọ wa ti nwọn nṣiṣẹ labẹ Ijọba ti nwọn kan wulẹ ngbe si ipo giga ṣugbọn ti owo wọn ko pọ tobẹ.

(3) Emi yio gbe ẹnu le ọrọ Apili lati ma gbe lọ si iwaju bi ilu Gambia, ilu Saro ati ilu Aganyin lati ma pe awọn enia wa ki nwọn ba wa yẹ ẹ wo.

Ki iṣe Apili bẹ kọ ni mo nwi lori ọna ti ofin ni.

(4) Ati nipa awọn Dokita wa ti nwọn nlọ si ilu Oyinbo lọ kọ iṣẹ ti nwọn si ngba iwe iṣẹ bọ lat ilu Oyinbo ti nwọn ki isi gba wọn si ibi iṣẹ Ijọba nihin.

(5) Nipa Kotu awọn Enia Dudu ti ilu Oke ti nwọn ki jẹki awọn Lọya ma lọ rojọ nibẹ; mo ti fi ọrọ Kotu na si iwaju Ijọba ri, ṣugbọn Ijọba ko jalẹjalẹ mo si tun ngba ni aniyan nisisiyi pe ti mba de Kansulu lọtẹ yi, ngo tun sọlu ọrọ na. Ati nipa Kotu ti awọn kan nda lamọran ni ilẹ yi nigba

kan, nwọn ro titi nigbana, nwọn gbe si iwaju awọn Ijọba, awọn pẹlu awọn Oyinbo Onişowo tabi awọn Oyinbo omiran ti ko si ninu işẹ Ijọba taku, nwọn si pa ọran na ti, awọn Igẹsi nwọn ki idanu le igi kan nwọn a fẹ gun, şugbọn bi nwọn ti ndanu le, bẹni awọn yio ma ta a kulẹ.

Nipa bi awọn Ijọba ti nnawo Bode tabi awọn owo omiran eyiti awọn ilu nsọ wipe kini awọn ti awọn tilẹ yan si Kansulu tilẹ nşe nibẹ gbanran, ti ti nwọn ki dasi awọn iru nkan bẹ.

Awọn mẹta ni ti ilu ni Igbimọ Ijọba ko awon enia jantirẹ wa si Igbimọ, iwọn iba ni enia mẹta le şe larin ogunlọgọ enia.

Nwọn pa aşẹ fun wọn lati ilu Oyinbo pe ki Ijọba yan awọn Igbimọ pataki kan lati ma ri yẹkinni bi nwọn ti nna owo si, nigbati nwọn wadi rẹ lọ wadi rẹ bọ, awọn ara wọn papa sọ wipe inakuna ni nwọn nna owo nitotọ.

Emi nko jafara lati ọdun karun, ohun ti a ba ri wipe Ijọba sẹ ti ko ba yẹ on yio ke, ti nwon ba si mu ọrọ kan wa si Igbimọ ti o ba dara fun ilu, on yio sọ wipe o dara, eyiti ko ba yẹ, on yio taku le lori, emi nko şe ọkan meji si ẹgbẹ yi, nitoripe ire lo jẹ fun ilu, Ọlọruu ko si jẹki o şe rere na delẹ fun wa.

Awọn kan ma nsọ wipe ẹgbẹ yi ntako Ijọba, awọn si ma nsọ wipe ọran ko jẹ bẹ arara.

Nitotọ ẹgbẹ yi lo yan mi, Ilọ ti mo lọ si ibẹ ki işe fun rere ẹgbẹ yi nikan, emi nlọ ja fun gbogbo ilu ni.

ỌGBẸNI SHACKLEFORD :—Ẹ ti gbọ gbogbo bi Moore ti leri leka, emi si ro wipe o tẹ nyin lọrun, ẹni oju rẹ ba to ọrọ ki o wa wi, oju Loya Moore ti ri nkan, ti a ba ni ki a yan enia si Kansulu, Lọyọ Moore ni o yẹ ki a mu, o mọ bi enia tişe nşe ilu, oyi gbogbo rẹ ti da leju rẹ kanpe.

LỌYA DOHERTY :—Mo ki gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ patapata, mo ro wipe nko tun nşe ajeji fun nyin mọ, ẹnyin ni ẹ yan mi si Igbimọ-Ilu nigbati mo sọ wipe emi yio ran nyin lẹru, kini emi kekere yi tilẹ jẹ papa ti mo fi sọ wipe mo nfẹ ki ẹ dido fun mi, ki nle lọ jẹ ọkan ninu Aşoju nyin ni Igbimọ Aşofin.

Ilu yi li a bi mi si, ọmọ ile yi hanunhanun ni mi, rere ilu yi ni mo si nfe, mo si mura lati ma ke kanran fun rere ilu yi, mo si mura lati şe gudugudu meje ti ẹdẹ nşe ti mba de Kansulu ani ti mba gbe ẹru nyin ka'ri.

Mo mọ ohun ti o nda ilu yi lamu loni, nkan ni ọran òwó (*Trade*) kosi owọ ni ilu yi, mo si nfẹ şa agbara mi ki inira ilu yi le dinku.

Nipa awọn Oyinbo Onişowo ati awọn Oyinbo Kọra, bi o ba de ibi kan pe o nigbo ifẹjẹ geregan ni o ti ma ba awọn Oyinbo-Onişowo nibẹ, o tun gbe ibẹ, awon Kọra kẹ tun nşe tiwọn lọ, bẹ òwó *Trade* ko ri bi o ti ri yi nigba ti awọn baba awọn.

Lẹhinna nipa awọn Oyinbo Onişowo ti nwọn nko Iwọn—*Scale* ati Tapo lọ si ọja Ejinrin ti nwọn ki jẹki Ekurọ, Epo ati Koko tun le ma de ibi bi o ti nwa ri, nipa ẹkọ awọn ọmọ wa eyiti Lọya Moore nsọrọ le lori pẹlu.

Bi mo ti dura gbagba lori ẹru ti ẹ kọ di ru mi bẹni mo tun mura lati duro lori eyi na pẹlu.

ALAKOSO :—Ẹ gbo bi Doherty papa ti şe alaro tirẹ si, mo si ro wipe o tẹ nyin lọrun: Oloye Oluwa nfẹ ba nyin sọ gbolohun meji, ki ẹ şe suru ki gbọ ohun ti yio sọ.

OLOYE OLUWA :—Mo ki gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ patapata ati ẹnyin iya wa gbogbo ti o mbẹ nihin loni yi.

A ba rere ilu yi wa si ihin lọsan yi, ẹ gbọ gbogbo ohun ti nwọn wi nihin loni, mo si ro wipe ẹ gbọ gbogbo bi Lọya Moore ti leri si.

Nigba kan Ijọba ri wipe o tọ ki nwọn fi Lọya Moore si Igbimọ tun arawọn, o si mbẹ nibẹ titi, nigbati o si şe, a gba nkan wa lọwọ wọn.

Lọya Moore ja fun ilu yi, o ja fun wa pupọ, şugbọn koi ti to fun Moore, ti ọtẹ yi ko jọ ti ijelo, awọn fẹ ki o şişẹ lọtẹ yi ki o ju ti ijole lọ.

Ẹ ko gbọ bi Owe kan ti lọ, ọkunrin kan wa adanu ni, o ni ki obinrin on se obẹ fun on, ngbati obinrin rẹ ma se ọbe na, o lọ ko ila, o ra gbogbo ohun-elo, o se ọbẹ ila yi fun ọkọ rẹ, nigbati o se e tan, o gbe kalẹ o ja de lọ, ilẹ ọjọ na şu ki o to de, nigbati ọkọ rẹ tẹ jẹun, o bu ọbẹ ila na, bi o ba ti ni ki on run'bọ, gbogbo ọbẹ a ma jo silẹ, gbogbo ilẹ kun fun obẹ—Nigbati obinrin rẹ de, o lọ ba ọkọ rẹ, o ni i i lere pe o ti jẹun, ọkọ na ni on ti jẹun, o ni njẹ o gbadun ọbẹ na, ọkọ ni ki o wo gbogbo ilẹ bi on ti gbadun rẹ si—Ariwo ẹgba la ge.........e!

Awa lara ilẹ yi bale ni wa, Lọya Moore obinrin wa ni, a fun ẹ ni owo ọbe, bi o ti se ọbẹ na si on papa ri, o ni on yio şe dokita gbogbo arun ti o mba wa ja, ẹru yi ẹyin (*egg*) ni, ẹniti a ba gbe le e lori, Ọlọrun nikan lo le şe atilẹhin fun oluwarẹ.

Lẹhinna o tun fi ẹnu kan oro Lọya Doherty gẹgẹbi o ti jẹ wipe gbogbo minu lati lọ si Kansulu ati gbogbo gẹgẹbi on na ti leri fun wa.

OLOYE OLUWA :—Nigbati a mu Lọya Doherty, awọn ẹiomiran nwọn si i wipe ọmode kekere ni ẹ o mu, şugbọn awa nsọ wipe ọmọde oran yi, ki işe oran ọmọde, bi o ba ti nbojuto ohun ti awọn ran lọ fun u, ti ko de ohun tan, ki o mu ti ararẹ şe ọran ti buşe, ẹ ko gbọ bi Owe kan ti wi, adiẹ njẹ igbado o ni on ko ni ehin, awọn ti o ni ehin nkọ nwọn nla ckuta.

Lẹhinna li o wa ntẹnumọ wipe lori ipade ti awọn ṣe nihin loni ti awọn si ti fi ipinnu le e, ko yẹ ki a tun ri awọn ẹgbẹhin ba ẹbọ jẹ.

ALAKOSO:—Lagbara Oluwa a o tun ṣe ipade kan nihin, ni ọjọ Satide to mbọ (Satide ti oni) ipade na arakuyamu ni fun gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ ati fun awọn alejo, nitorina bi o ba di ojọ na ki ẹnyin onile fun awọn alejo laye, nitoripe boya ni awọn yio tun ṣe ipade omiran lẹhin nyẹn ki ọjọ na to ko.

Emi ni ti nyin nitotọ,
KEKERE-AWO.

---

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Mo bẹrẹ foji o.

Mo kọwe kekere yi lati fi da Kekere Awo lohun ọrọ ti o sọ sinu iwe rẹ ti ijọ kẹjọ oṣu yi (8th Sept), ti o bẹrẹ bayi "Oluwa jọwọ dakun".

Mo ka iwe na pẹlu ẹdun ọkan ṣugbọn nigbati mo ri ibiti Kekere Awo gbe bere esi, ọkan mi fuyẹ diẹ, mo si gbe kalamu mi lati sọ ọrọ ṣoki yi fun idahun; ṣugbọn ẹru ba mi nigbati mo ro wipe awọn ẹniti o ba kawe yi yio ro wipe mo nṣe yẹyẹ ni. Jọwọ ọmọ iya, nko ṣe yẹyẹ.

Idahun mi na ni yi o. Ki airiṣẹ airowoṣe, ailowolọwọ nwọnyi to kasẹ nilẹ afi:—

1. Bi Ijọba ba le fi opin si iwọn owo ti awọn olowo ni lati ni ni Banki ki nwọn ki o si ṣe ofin pe ki nwọn simi fun iye ọdun kan laiṣowo titi iye ọdun na yio fi pe.

2. Bi Ijọba ba le sọ iye enia ti ẹnikọkan ni lati ma tọju nipa fifi nwọn sabẹ, gẹgẹbi owo ti oluwarẹ ni lọwọ ba ti to.

3. Bi Ijọba ba le ṣe ofin ẹniti yio ni aṣẹ lati na ju iye owo kan lọ fun igbeyawo tabi nkan bẹ laigbọdọ ju bẹ, lọ nipa mimọ elo ni oluwarẹ ni lọwọ.

4. Bi ofin ba le wa fun elo ni enia ni lati ma fi fẹ obinrin lọwọ awọn obi rẹ laigbọdọ le, laigbọdọ din.

5. Bi Ijọba ba le paṣẹ fun gbogbo awọn oniṣowo wipe ki nwọn jẹki awọn kọkọ ri iwe ọja (Invoice) ẹniti o ba fẹ ra ọja ju iye kan lọ lati wadi bi iye ti oluwa rẹ ni lọwọ yẹ fun ati ra iru ọja tabi wọ iru aṣọ ti owo rẹ ga bẹ.

6. Bi Ijọba ba le fi opin si iye ọmọ ti ẹnikọkan ni lati ma bi mọ, ati wipe bi oluwarẹ ba ti bi to bẹ gẹ, ki o bẹrẹ si wa nkan mu ti on ko fi ni bi omiran mọ tabi ki o bẹrẹ si lo egbogi ti yio fi jẹ pe bi oluwarẹ ti lowo mọ ni yio le bimọ mọ.

7. Bi Ijọba ba le paṣẹ wipe ẹniti ko ba ni iye owo bayibayi lọwọ ko gbọdọ fẹ obinrin tabi ko gbọdọ gbidanwo lati bimọ, tabi ẹniti o ba fẹ ni iyawo tabi ni ọkọ ni lati mu Iwe Banki rẹ lọwọ, ki o si wa fi han ni Office bayibayi ki o to fi iyawo rẹ sọdọ tabi ki o to lọ sọdọ ọkọ rẹ.

8. Bi Ijọba ba le ṣe ofin wipe iye bayibayi ni awọn ara ilu ni lati ma ta ọja bayibayi fun ara nwọn.

9. Bi Ijọba ba le ma yọ owo ninu gbogbo owo awọn oṣiṣẹ si apo gbogbo awọn ọmọ alainiya.

Emi ni tirẹ nitotọ,
TAIWO.

---

## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣeṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

## IGI MA DA O.

Ko si ẹniti ko yọ ni ọsẹ ti o kọja nigbati a ri pe Adajọ Agba sọpe on gba Apili fun ẹjọ Ọgbẹni Macaulay; Adajọ Agba na si sọpe on tanmọ pe aṣiṣe mbẹ ninu Idajọ ti Adajọ kekere da lẹhin igbati on ti ka ọrọ idajọ na tan: o si sọfun Lọya Ọgbẹni Macaulay pe ki o lọ wa Ofin kan wa ti o fun on Adajọ Agba ni ipa lati bẹ Idajọ na wo: o si ni bibẹkọ ki Lọya rẹ lọ ṣe *Motion* miran, ki ẹjọ si sun fun ọjọ meje:

Anu si ṣe ni pe ni ijẹta ti nwọn fọn si ariyanjiyan ẹjọ yi, ni Ganran Adajọ Agba ni on ko tun ri si ẹjọ na mo, bẹ si ni on ko tun ri si ẹjọ ti Dokita Kọlkriki.


## KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ ṣe ariya ti Iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe Wolimọ lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe ariya nipa ti oku lọ sibẹ, o wa fun ẹnikẹni opọku-oyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B. SHODIYA,
*Produce Buyer*,
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.



# NIGERIAN RAILWAY

## *Numerous Improvements*

Commencing MONDAY, 1st OCTOBER, 1928.

Additional and better Trains.

Cheaper Return Fares.

***Easier Regulations Regarding Luggage, Produce, etc.***

Apply to your Local Station Master for Pamphlet.

***Issued Free of Charge.***

Giving Full Particulars of all Trains between

***IDDO and LAFENWA***

New Reduced Fares and Revised Luggage Regulations.

***"Travel by Rail"***

"SAFETY" "SPEED"

"REGULARITY."

## ẸGBẸ DẸMỌ, Ẹ JI GIRI.

Ni ọjọ Satide oni ti iwe irohin wa yi jade on lo ma jẹki ọjọ idibo wa ku ijọ meje ti awọn enia bi marun ti a gbọ wipe wọn nfẹ lati lọ si Igbimọ nla ti aṣofin ti o jẹ wipe enia mẹta pere ni ara Eke to ni anfani ati yan enia sibẹ yio jalẹ ti ilẹ si ma mọ ni alẹ ọjọ *Friday* ijọ kejidilọgbọn oṣu yi ti gbogbo aniyan ati ero awọn ẹni marun yi ti yio fi ara ti si ibi kan. Bi a ba nri enia pupọ to fẹ ọl, ani lati mu ero kan dani eyi ni wipe ire ilu ni awọn enia wọnyi nfẹ, ki si iṣe ero wọn lati gbe ilu ta, eyi ti wọn ko ti jẹ ni ni agbara lati ṣe, ko si ẹniti oruko rere ko wun, ko si si ẹniti o fẹ jẹ oruko buburu ni ilu rẹ, lagbaja nfẹ "Honourable" lati jẹ, ko si ẹniti ko lẹ ka fi kun oruko on, ṣe awọn ẹnikan ni wọn ti njẹ "Heaourble" yi ri, ṣugbọn loni nkọ, nigbati ilu ko yan irufẹ ẹnibẹ ṣe wọn wa ọkọ wọn si tọ, awọn si fi ọran mọ Ọlọrun lọkan, nipa bẹ, ẹ joko si ẹnu mimi, ṣe inu ilu papa ni lati dun wipe awọn ẹni mẹta ti wọn yan si igbimọ iṣẹ ti wọn nṣe jẹ oriṣi mẹta, ṣugbọn bi gbogbo ẹni mẹta wọnyi jẹ Lọya ko buru, bi nwọn si jẹ Dokita bakanna bi wọn si jẹ Wọnlẹwọlẹ gẹgẹ lo ṣe, bi wọn si jẹ Onişowo bakanna ni, ki awọn mẹtẹta yi ṣe, ki ọkan jẹ Lọya, ki ọkan jẹ Dokita, ki ọkan si jẹ wọnlẹ-wọnlẹ *Surveyor* ki lo ti ma dun te, ṣugbọn kini gbogbo nkan nlọ si rere, ni ilẹ alaye.

Ni ọjọ Satide to kọja, ẹniti o jẹ alaga ni Igbimọ Ẹgbẹ Dẹmọ ti wọn ṣe ni ọjọ yi, o sọ wipe awọn igbimọ kan ninnu igbimọ ẹgbẹ yi wọn kun sinu nipa ẹnikẹta ti wọn yan, wipe ko i ti ni oye to, tabi ko i ti ni iri si aiye, agba eyi to wi yi si otitọ nitori pe bi nkan ba wa ninu enia ti ko ba ti sọ sode o le wu pupọ nitori irufẹ iwa bẹ o le mu Jamba wa ba ẹgbẹ ki Ọlọrun ma jẹ ki awa Dẹmọ ri irufẹ nkan bẹ, lọna keji ẹwẹ, gẹgẹ bi aşa awọn oyinbo ti wọn fun wa ni aye ati anfani lati ma yan enia si Igbimọ wọn ko da ọrọ na silẹ nitori ẹgbẹ kan bi ko ṣe nitori anfani ilu, ṣugbọn nigbati awa ẹgbẹ Dẹmọ to jẹ wipe nkan ti a nṣe o dara loju gbogbo ilu on lo jẹ ki ẹniti a ba mu lati lọ si Igbimo ki iyẹn han gbangba wipe ẹgbẹ yi lo ni ilu, ati wipe gẹgẹbi a ti ṣe yan enia, lati igba ti Lọya Shyngle *(Ologbe,)* Lọya Moore ti o şi wa ninu ẹgbẹ Dẹmọ ati Dokita Jones ṣe yinyan enia na lo jẹ ki awọn ẹgbẹ pataki bi "Young Nigerians" ki wọn pẹlu wa, nipa ni ẹniti a ba yan sibẹ, nipa bẹ, iyẹn lo jẹ ki ilosiwaju ẹgbẹ wa ko yan ju niwaju enia ati niwaju Ọba to da wa,

Nipa ọrọ alaga ẹgbẹ Dẹmọ ijọ Satide sọ nipa wipe ninu awọn Igbimo ti nwọn ṣe aşaro nipa awọn ẹniti wọn ma lọ si Igbimọ ninu wọn, wọn ta ko ẹniti nwọn yan şikẹta wipe ko ti ni oye a ti ṣe ilu lori, nipa ọro bayi loju ti wa, o ma nmu irẹwẹsi ọkan wa fun ọmọ ẹgbẹ to nipa a ti dibo ni, şugbọn kini ọpọlọpọ awọn ẹlomiran nsọ wipe bo ṣe ọbọ ni ẹgbẹ pataki ẹgbẹ Dẹmọ mu wa lati lọ si Igbimọ awọn yio ṣe atilẹhin fun irufẹ ẹnibẹ, ẹnyin enia wa ẹ ma jẹ ki ominu ko kọ nyin, nipa awọn ẹni mẹta ti ẹgbẹ wa yi mu, ti awa ọmọ ẹgbẹ ni lati ṣe ko kari wipe ki ẹsẹ wọn ko wọ Igbimọ nla yi nipa idibo yin ni ododo la laişe oju saju ẹniti o ba wa duro ti ẹgbẹ to ba wa, ko duro şinşin, ẹniti ifẹ inu rẹ ba ṣe ni ki o ṣe la lai boju wo ẹhin, nipa awọn ẹniti ifẹ inu wọn ntọ wọn si ọna ti wọn ma hu, bẹni ifẹ inu awọn enia wa pataki ntọ wọn lati duro wipe wọn ma lọ, ki ṣe lati fọ ẹgbẹ Dẹmọ ti wọn ba wọle, ṣugbọn fun ire ilu ni wọn ṣe fẹ lọ wipe ki ilu Gbogbo-gbo ki wọn dibo fun on, ṣe ninu aọwn ẹniti wọn fẹ gba ọdọ ẹgbẹ Dẹmọ lo, to si jẹ wipe ki ṣe ifẹ inu ẹlomiran lati wa wọ ẹgbẹ ti wọn si fẹ lọ si Igbimọ ẹtọ ti wọn ni lati duro şinşin la lai yẹsẹ, ṣe awọn aşiwere enia lo ma sọ wipe kilo ṣe ti wọn ko fẹ gba ẹgbẹ Dẹmọ lo, ṣe awọn ẹniti ko wa si ọdọ wa wọnyi ṣe wọn ko ṣe laifi kan si wa ri, ṣe wọn mọ wipe iwọ James, iwọ Amọdu, iwọ Braimah tabi awọn ẹlomiran o wa ninu ẹgbẹ Dẹmọ, ki wọn to fi iwe ranşẹ si ọ wipe awọn fẹ lọ, ki o dibo fun on, ọran yi ko mu ija wa, ẹ gbọ bi oloye Oluwa ti sọ ni ipade wa ti ọjọ Satide wipe nigbati o nsọ ọrọ nipa awọn ẹniti o fẹ lọ si Igbimọ, nipa owe ti o pa wippe ọbẹ kere ko kere bo ba ti ran ori ko buşe, tabi ẹgbọ eyi ti o pa nipa ọrọ àdamu on pelu aya rẹ, ẹniti ko ni ẹnu ti iyawo rẹ la se ọbẹ ila, to jẹ wipe bi ọkọ ba ma jẹun bo ba bu ọbẹ ẹnu rẹ a jo ati ọka ati ọbẹ na du, tabi ko dun to so wipe iwọ wo gbogbo ilẹ. ti oloye Oluwa sọ wipe awa ẹgbẹ Dẹmọ ni àdamu, Lọya Moore ni iyawo wa, nitori na gbogbo ẹnyin ẹkawe wa, ẹ o ri aiye lode ba yi, ẹ ko wa mọ ibi ti koko owe yi pari si, a fi aye silẹ fun nyin lati tumọ rẹ.

(*a o ma ba bọ*)

Emi ni ti nyin nitotọ,
ENIA KO DA BI ALLAH.

---

Ipade Ẹgbẹ Dẹmọ tun wa ni oni ni Glover Memorial Hall, l'Ẹhingbẹti ni agogo mẹrin irọlẹ. A ke si gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ lati tete de.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ęda ati gbogbo arun ti ki ję ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.

41, Offin Road, Lagos.

*N.B:- Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Aboyun, Iju, Ęda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.

**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.

41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*

The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA EJĘ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu ię mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ęda ti o ba gbo, Ęyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, **Ęsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.**

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— :o: ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.